**39.** Ina Jahimi ni yio jẹ ibugbe (rẹ̀).

فَإِنَّ ٱلۡجَحِيمَ هِيَ ٱلۡمَأۡوَىٰ ٣٩

**40.** Ṣugbọn niti ẹniti o paiya lati duro niwaju Oluwa rẹ̀, ti o si ko ara rẹ̀ nijanu kuro nibi ifẹ̃nu.

وَأَمَّا مَنۡ خَافَ مَقَامَ رَبِّهِۦ وَنَهَى ٱلنَّفۡسَ عَنِ ٱلۡهَوَىٰ ٤٠

**41.** Dajudaju ọgba idẹra ni yio jẹ ibugbe (rẹ̀).

فَإِنَّ ٱلۡجَنَّةَ هِيَ ٱلۡمَأۡوَىٰ ٤١

**42.** Nwọn yio bi ọ lere akoko pe nigbawo lo ma de.

يَسۡـَٔلُونَكَ عَنِ ٱلسَّاعَةِ أَيَّانَ مُرۡسَىٰهَا ٤٢

**43.** Ko si imọ rẹ ni ọdọ rẹ (iwọ Annabi; ọna wo ni iwọ fi le wa ranti tabi se iwadii rẹ)?!

فِيمَ أَنتَ مِن ذِكۡرَىٰهَآ ٤٣

**44.** Ọdọ Oluwa rẹ ni opin (mimọ̀) rẹ̀ wà.

إِلَىٰ رَبِّكَ مُنتَهَىٰهَآ ٤٤

**45.** Dajudaju Irẹ jẹ olukilọ fun ẹniti mbẹru rẹ̀ (ajinde).

إِنَّمَآ أَنتَ مُنذِرُ مَن يَخۡشَىٰهَا ٤٥

**46.** Ni ọjọ ti nwọn ba ri i, yio dabi ẹnipe nwọn kò ṣe ju aṣãlẹ kan tabi owurọ kan lọ (laiye).

كَأَنَّهُمۡ يَوۡمَ يَرَوۡنَهَا لَمۡ يَلۡبَثُوٓاْ إِلَّا عَشِيَّةً أَوۡ ضُحَىٰهَا ٤٦

## *(80) Suratu - 'Abasa*

سُورَةُ عَبَسَ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** O roju ('Abasa) o si yipada.

عَبَسَ وَتَوَلَّىٰٓ ١

**2.** Nitoripe afọju na wa ba a.

أَن جَآءَهُ ٱلۡأَعۡمَىٰ ٢

**3.** Atipe kini o le mu ọ mọ amọdaju pe on le ṣe mimọ́.

وَمَا يُدۡرِيكَ لَعَلَّهُۥ يَزَّكَّىٰٓ ٣

**4.** Tabi on yio gba iṣinileti ti iṣinileti na yio fi ṣe e ni anfani?

أَوۡ يَذَّكَّرُ فَتَنفَعَهُ ٱلذِّكۡرَىٰٓ ٤

**5.** Şugbọn ẹniti o ti to tan.

أَمَّا مَنِ اسْتَغْنَىٰ ﴿٥﴾

**6.** Iyẹn ni irẹ dojukọ.

فَأَنتَ لَهُ تَصَدَّىٰ ﴿٦﴾

**7.** Atipe kò si ẹṣẹ kan fun ọ bi on kò ba ṣe mimọ́.

وَمَا عَلَيْكَ أَلَّا يَزَّكَّىٰ ﴿٧﴾

**8.** Atipe irẹ ri ẹniti o wa ba ọ ti o nkanju (lati de ọdọ rẹ).

وَأَمَّا مَن جَاءَكَ يَسْعَىٰ ﴿٨﴾

**9.** Atipe on si npaiya (Ọlọhun).

وَهُوَ يَخْشَىٰ ﴿٩﴾

**10.** Bẹni irẹ kò kọbiarasi i.

فَأَنتَ عَنْهُ تَلَهَّىٰ ﴿١٠﴾

**11.** Kò tọ rara, dajudaju on (Al-Kurani) jẹ iranti.

كَلَّا إِنَّهَا تَذْكِرَةٌ ﴿١١﴾

**12.** Nitorina ẹniti o ba fẹ ki o gba iranti na.

فَمَن شَاءَ ذَكَرَهُ ﴿١٢﴾

**13.** Ninu Tirà ti a pọnle.

فِي صُحُفٍ مُّكَرَّمَةٍ ﴿١٣﴾

**14.** Ti a gbe ga, ti a ti fọ mọ.

مَّرْفُوعَةٍ مُّطَهَّرَةٍ ﴿١٤﴾

**15.** Pẹlu ọwọ awọn akọwe.

بِأَيْدِي سَفَرَةٍ ﴿١٥﴾

**16.** Awọn alapọnle, awọn oluşe rere.

كِرَامٍ بَرَرَةٍ ﴿١٦﴾

**17.** Egùn ni fun enia, kini ohun ti o mu u ṣe aimore!

قُتِلَ الْإِنسَانُ مَا أَكْفَرَهُ ﴿١٧﴾

**18.** Kini (Ọlọhun) fi da a?

مِنْ أَيِّ شَيْءٍ خَلَقَهُ ﴿١٨﴾

**19.** Ninu omi gbọlọgbọlọ ni O ti da a. O si pebubu rẹ̀.

مِن نُّطْفَةٍ خَلَقَهُ فَقَدَّرَهُ ﴿١٩﴾

**20.** Lẹhinna O ṣe ọna irọrun fun u.

ثُمَّ السَّبِيلَ يَسَّرَهُ ﴿٢٠﴾

**21.** Lẹhinna yio pa a. A o si sin i (sinu sãre).

ثُمَّ أَمَاتَهُ فَأَقْبَرَهُ ﴿٢١﴾

**22.** Lẹhinna nigbati (Ọlọhun) ba fẹ yio gbe e dide.

ثُمَّ إِذَا شَآءَ أَنشَرَهُۥ ﴿٢٢﴾

**23.** Sibẹsibẹ (enia) kò ṣe ohun ti (Ọlọhun) pa laṣẹ fun u.

كَلَّا لَمَّا يَقۡضِ مَآ أَمَرَهُۥ ﴿٢٣﴾

**24.** Nitorina ki enia ti ipa onjẹ rẹ woye.

فَلۡيَنظُرِ ٱلۡإِنسَٰنُ إِلَىٰ طَعَامِهِۦٓ ﴿٢٤﴾

**25.** Pe dajudaju Awa ni A nda omi na ni didà.

أَنَّا صَبَبۡنَا ٱلۡمَآءَ صَبّٗا ﴿٢٥﴾

**26.** Lẹhinna Awa nmu ilẹ na bu ni bibu pẹpẹ.

ثُمَّ شَقَقۡنَا ٱلۡأَرۡضَ شَقّٗا ﴿٢٦﴾

**27.** Awa si njẹ ki awọn horo ma hù jade ninu rẹ.

فَأَنۢبَتۡنَا فِيهَا حَبّٗا ﴿٢٧﴾

**28.** Ati eso ajara ati kannafuru.

وَعِنَبٗا وَقَضۡبٗا ﴿٢٨﴾

**29.** Ati igi ororo-didun (Setuni) ati igi dabinu.

وَزَيۡتُونٗا وَنَخۡلٗا ﴿٢٩﴾

**30.** Ati awọn ọgba ti o pọ ni igi.

وَحَدَآئِقَ غُلۡبٗا ﴿٣٠﴾

**31.** Ati awọn eso (ipapanu) ati awọn ewe ti ẹran njẹ.

وَفَٰكِهَةٗ وَأَبّٗا ﴿٣١﴾

**32.** O jẹ igbadun fun nyin ati fun awọn ẹran nyin.

مَّتَٰعٗا لَّكُمۡ وَلِأَنۡعَٰمِكُمۡ ﴿٣٢﴾

**33.** Atipe nigbati ọjọ ajinde na ba de.

فَإِذَا جَآءَتِ ٱلصَّآخَّةُ ﴿٣٣﴾

**34.** Ọjọ ti enia yio ma sa fun ọmọ iya rẹ.

يَوۡمَ يَفِرُّ ٱلۡمَرۡءُ مِنۡ أَخِيهِ ﴿٣٤﴾

**35.** Ati fun iya rẹ ati baba rẹ.

وَأُمِّهِۦ وَأَبِيهِ ﴿٣٥﴾

**36.** Ati iyawo rẹ ati awọn ọmọ rẹ.

وَصَٰحِبَتِهِۦ وَبَنِيهِ ﴿٣٦﴾

لِكُلِّ ٱمْرِئٍ مِّنْهُمْ يَوْمَئِذٍ شَأْنٌ يُغْنِيهِ ٣٧

**37.** Ti olukuluku enia, ni ọjọ na, ni yio to o ran.

وُجُوهٌ يَوْمَئِذٍ مُّسْفِرَةٌ ٣٨

**38.** Awọn oju kan yio mọlẹ ni ọjọ na.

ضَاحِكَةٌ مُّسْتَبْشِرَةٌ ٣٩

**39.** Nwọn yio ma rẹrin pẹlu idunnu.

وَوُجُوهٌ يَوْمَئِذٍ عَلَيْهَا غَبَرَةٌ ٤٠

**40.** Awọn oju miran erukuru yio bo wọn daru ni ọjọ na.

تَرْهَقُهَا قَتَرَةٌ ٤١

**41.** Okùnkùn yio bo (oju) wọn.

أُولَٰٓئِكَ هُمُ ٱلْكَفَرَةُ ٱلْفَجَرَةُ ٤٢

**42.** Awọn elewọnni ni awọn alaigbagbọ ẹlẹṣẹ.

## سُورَةُ التَّكْوِيرِ

## *(81) Suratul - Takwīri*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

إِذَا ٱلشَّمْسُ كُوِّرَتْ ١

**1.** Nigbati orùn ba di kika.

وَإِذَا ٱلنُّجُومُ ٱنكَدَرَتْ ٢

**2.** Ati nigbati awọn iràwọ̀ ba njabọ.

وَإِذَا ٱلْجِبَالُ سُيِّرَتْ ٣

**3.** Ati nigbati awọn òkè ba di ohun ti a kù dànù.

وَإِذَا ٱلْعِشَارُ عُطِّلَتْ ٤

**4.** Ati nigbati awọn aboyun rakunmi ba di ohun ti a pati.

وَإِذَا ٱلْوُحُوشُ حُشِرَتْ ٥

**5.** Ati nigbati a ba ko awọn ẹranko jọ.

وَإِذَا ٱلْبِحَارُ سُجِّرَتْ ٦

**6.** Ati nigbati awọn ibudò ba ngbina.

وَإِذَا ٱلنُّفُوسُ زُوِّجَتْ ٧

**7.** Ati nigbati awọn ẹmi ba nsopọ mọ awọn ara wọn.